# BÍRÍKÌ LAI SI KORIKO

**Ẹksodu 5:1-23**

**ẸKỌ 50 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ọ̀pọlọpọ ni ipọnju olododo: ṣugbọn OLUWA gbà a ninu wọn gbogbo" (Orin Dafidi 34:19).**

## Isin Ibọriṣa ni ilẹ Egipti

Mose ati Aarọni ni igbẹkẹle ninu awọn Ọmọ Israẹli, ṣugbọn wọn ni lati lọ siwaju Farao sibẹ -- wọn si mọ̀ pe oun yoo kọ ẹ̀bẹ̀ wọn. I ba ṣe pe wọn kò ni idani-loju pe Ọlọrun wà pẹlu wọn, boya ni wọn i ba ti ni igboya to lati duro niwaju ọba abọriṣa yii, ki wọn si beere àye fun ọkẹ aimoye eniyan ti o fi n ṣe ẹrú lati lọ si aginju ki wọn ba le sin Ọlọrun ti oun kò mọ ohunkohun nipa Rẹ̀ rárá.

Awọn ti o n ṣe awari nipa ohun ilẹ ti igba aye atijọ ni ẹri nipa Egipti pe, o kere tan o to ẹgbọ̀kànlá (2,200) oriṣa ti awọn ara Egipti n sìn. Bi Farao ba ni oriṣa ti o pọ̀ pupọ bayii, ki ni ṣe ti yoo feti silẹ si Ọlọrun awọn ẹrú rẹ̀? Ṣugbọn a o ri i pe ki Ọlọrun to pari iṣẹ Rẹ̀ pẹlu Farao, o ti sọ gbogbo igbẹkẹle ti o ni ninu awọn oriṣa rẹ nù.

## Ipọnju Di Pupọ

Gbogbo ohun ti Farao n fẹ ni ki awọn ọmọ Heberu sa ṣiṣẹ pupọ fun oun lọfẹẹ. Eku-káká ni awọn eniyan Ọlọrun yii fi n ri ounjẹ jẹ to lati mu wọn wà laaye, sibẹ wọn ni lati ṣiṣẹ karakara. Nigba ti Mose ati Aarọni sọ fun un pe ki o fun awọn eniyan wọnyii ni ọjọ diẹ lati lọ si aginju ki wọn ba le sin Ọlọrun, Farao ṣe aroye pe awọn eniyan wọnyii kò ni iṣẹ to lati ṣe, nitori bẹẹ ni wọn ṣe ni àye lati rò nipa ohun ti kò ni laari bi rirú ẹbọ. O bi i ninu to bẹẹ gẹẹ ti o mu ki wọn ṣiṣẹ karakara ju ti atẹyinwa lọ, dipo ki o fun wọn ni isinmi. Kò tun fun wọn ni koriko lati ṣe biriki mọ́, sibẹ a fi ipá mu wọn lati ṣe iye biriki kan naa ti wọn ti n ṣe tẹlẹ. O ro pe nipa ipọnju ti o pọ̀ pupọ bayii, oun le mu ki o sú wọn lati tun maa ronu ohun ti wọn n fẹ.

Awọn onroro alakoso wà ni igba ayé ti wa yi, ti wọn rò pe awọn le ṣe bakan naa. Ni orilẹ-ede miiran awọn ẹrú maa n gbé ni ibi ti kò dara, a si maa n lo wọn ni ọna ti o buru ju bi a ti le lo ẹranko lọ. A kò gbà wọn laaye lati ronu fun ara wọn. Ṣugbọn Ọlọrun ti fi ẹmi sinu olukuluku eniyan, a kò si le pa ẹ̀dá eniyan run. Ifẹ kan maa n wà ninu ọkàn eniyan fun ohun ti o dara; nigbakiigba ti o ba si ṣe e ṣe, oun yoo bọ́ ajaga awọn aninilara rẹ̀ kuro.

## "Gbẹkẹle E, si Gbọran"

Awọn Ọmọ Israẹli ni ireti pe idasilẹ yoo de lai pẹ, nisisiyii ti a si mu ẹru wọn wuwo si i ju ti atẹyinwa lọ, wọn bẹrẹ si ṣiyemeji boya Ọlọrun tún wà fun wọn mọ́. O ya Mose paapaa lẹnu bi nnkan yii ṣe le ri bẹẹ. Njẹ ọna ti Ọlọrun yoo gbà mu ileri Rẹ̀ ṣẹ ni yii?

Ọlọrun n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ gbẹkẹle E. Nigba miiran nigba ti ara ẹni kan bá ṣe alai dá, ti o si n gbadura si Ọlọrun fun iwosan, dipo ki o sàn, n ṣe ni yoo buru si i. Eyi ki i ṣe igba ti o yẹ ki o sọ igbagbọ́ rẹ̀ ninu Ọlọrun nù, ṣugbọn o ni lati sinmi le Oluwa si i Ẹni ti O wi pe, "Emi li OLUWA ti o mu ọ lara dá" (Ẹksodu 15:26). A maa n gbọ́ ọrọ̀ wọnyii nigbakuugba pe, "Okunkun maa n bolẹ pupọ ju lọ ni afẹ̀mọ́júmọ́." Nigba miiran o maa n ya wa lẹnu bi nnkan ṣe le buru si i fun wa, ti idanwo pupọ si tubọ maa n bá wa! Ṣugbọn Ọlọrun ti ṣeleri pe oore-ọfẹ Oun tó fun wa. O fẹ ki awọn eniyan ti Oun gbẹkẹle Oun patapata, ki wọn si duro titi ifẹ Rẹ̀ yoo fi ṣẹ.

Ọlọrun le jẹ ki ipọnju de ba wa nigba miiran, tabi ki O yiiri wa wò lọna miiran to bẹẹ gẹẹ ti a kò le da ohunkohun ṣe fun ara wa rara. Lẹyin naa nigba ti Ọlọrun ba gbà wá, ko si ẹni ti yoo gba ogo naa fun ara rẹ̀ bi ko ṣe Ọlọrun.

Nitori Ọlọrun kò rán idasilẹ wá ni igba kin-in-ni ti Mose ati Aarọni beere fun un, kò fi han pe Oun ko ni mu ileri Rẹ̀ ṣẹ. Ọrọ Ọlọrun kò le yẹ̀. A o ri ninu ẹkọ wa niwaju pe ni akoko ti Ọlọrun, O mú awọn eniyan Rẹ̀ jade pẹlu ọwọ agbara, eyi ti Mose maa n rán awọn Ọmọ Israẹli leti nigbakuugba, gẹgẹ bi a ti ri i ninu Deuteronomi 5:15 – "Si ranti pe iwọ ti ṣe iranṣẹ ni ilẹ Egipti, ati pe OLUWA Ọlọrun rẹ mú ọ lati ìbẹ̀ jade wá nipa ọwọ agbara, ati nipa ninà apa." Lẹyin ọpọ ọgọrun ọdun, nigba ti awọn Ọmọ Israẹli tún wà ni oko-ẹrú, ni akoko yii labẹ awọn ara Babiloni, Daniẹli ranti idasilẹ nla yii, o si gbadura bayii pe, "Oluwa Ọlọrun wa, iwọ ti o ti fi ọwọ agbara mu awọn enia rẹ jade lati Egipti wá …" (Daniẹli 9:15).

A gbọdọ kọ ẹkọ ninu eyi pe kò si ohun ti o ṣoro fun Oluwa, a o si yọ̀ pupọ bi a bá le gbẹkẹle E patapata. "Duro de OLUWA; ki o si tújuka, yio si mu ọ li aiya le: mo ni, duro de OLUWA" (Orin Dafidi 27:14).

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni idahun Farao fun ibeere Mose ati Aarọni pe ki o fun awọn Ọmọ Israẹli ni àyè lati lọ?
2. Bawo ni a ti ṣe fi kún ipọnju awọn eniyan wọnyii?
3. Njẹ o rò pe Oluwa fiye si ipọnju awọn eniyan Rẹ̀?
4. Njẹ Ọlọrun ṣeleri lati pese "ọna abayọ" fun wa, nigba ti a ba n dán wa wò?
5. Njẹ o ro pe Mose rẹ̀wẹsi nigba ti o gbadura fun awọn eniyan naa?